BIBA ẸNIRERE SỌRẸ ATI ORIPA RẸ LORI ẸNIKỌỌKAN

Awọn erongba khutuba

- Rire musulumi kọọkan lori ilana ati iwa isilaamu
- Wiwani nisọra kuro nibi awọn ẹni buruku, ati pipanilasẹ biba awọn mumini rin.
- Titẹnpẹlẹ mọ rire awọn ọmọbinrin ati sisamojuto awọn ti wọn nba a sọrẹ

Akoko khutuba: isẹju marundinlogoji

الحمد لله رب العالمين شرع لنا دينا قويما ، وهدانا صراطا مستقيما ، وأشهد أن لا إله إلا الله وحده لاشريك له وكفى بالله عليما ، وأشهد أن محمدا عبده ورسوله حثّ على صحبة الصالحين صلّى الله عليه وعلى آله وأصحابه وكل من اتّبعه وسلم تسليما . أما بعد:

Ọpẹ ni fun Ọlọhun ọba, Alaanu julọ, oloore ọfẹ. Mo jẹri pẹ kosi ẹniti ijọsin ododo yẹ, ayafi Ọlọhun nikan, ko lorogun ko lafiwe, bẹẹni mo si jẹri pe Annọbi wa Muhammed ẹrusin Ọlọhun ni, o pawa lasẹ lati sẹsa ọrẹ rere barin bẹẹni o si wawa nisọra nibi ọrẹ buruku ikẹ ati igẹ Ọlọhun ki o maa ba Anọbi wa, awọn ara ile rẹ awọn ẹmẹwa ati gbogbo ẹlẹsin isilaamu lapapọ

Ẹyin mumini ododo, ẹ lọ mọ wipe dajudaju Ọlọhun da ẹda eniyan lẹniti ko nii maa dawa, da jẹun tabi maa sẹmi lohun nikan, bikosepe yoo bukata si ki o ropọ mọ ẹlomiran. Isilaamu si niyi, ẹsin to ba gbogbo adamọ mu ni, kódà, adamọ toba bajẹ isilaamu ni yoo tun un se, idi niyi ti Ọlọhun kofi da annọbi Adamọ loun nikan.

Ọlọhun sọ pe:

"هو الذى خلقكم من نفس واحدة وخلق منها زوجها ليسكن إليها"